# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OṢÙ KẸ́JỌ, ỌDÚN 2022

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸ́JỌ 2022 - DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN ẸMÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (6)

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

### OLÙGBÀLÀ, A TÚN FẸ́ F'OHÙN KAN

1. Olùgbàlà, a tún fẹ́ f'ohùn kan
Yin orúkọ Rẹ k'a tó túká lọ:
Ní'parí'sìn, a dìde láti yìn,
A ó sì kúnlẹ̀ fún ibùkún Rẹ.

2. F'àláfíà fún wa, b'a ti nrelé;
Jẹ́ k'a parí ọjọ́ yì pẹ̀lú Rẹ;
Pa ayà wa mọ́, sì sọ ètè wa
T'a fi pe orúkọ Rẹ nílé yì.

3. F'àláfíà fún wa l'óru òní;
Sọ òkùnkùn rẹ̀ dìmọ́lẹ̀ fún wa,
Nínú ewu, yọ ara ọmọ Rẹ
Òkùn òn 'mọ́lẹ̀ j'ọ́kanná fún Ọ.

4. F'àláfíà fún wa lọ́j'ayé wa
Rẹ̀ wá l'ẹ́kún k'O sì gbè wá ní'jà,
Lẹ́yìn gbogbo ìjagun ayé yì,
Pé wa, Bàbá, s'ọ́run alàfíà.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Ẹ̀mí Mímọ́, ayé mi ṣí sílẹ̀ fún Ọ lónì, wọ̀ mí láṣọ ògo Rẹ, ní orúkọ Jésù.
2. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, fọ̀ mí mọ́ kúrò nínú gbogbo ìwà aìmọ́ lónì, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára Ẹ̀mí Mímọ́ tí Ó yọ Pétérù kúrò nínú túbú, bẹ̀ mí wo lónì, kí O sì túmisílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ohun gbogbo tíkò ṣàfihàn awòrán Krístì nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹ̀mí Mímọ́, wọnú ayé mi, kí O sì jẹ́ kí òkùnkùn kúrò lọ́dọ̀ mi lónì, ní orúkọ Jésù.
5. Agbára Ọ̀gá Ògo Jùlọ, bàlé mi báyìí, kí O sì ṣọmí di pípé, ní orúkọ Jésù.
6. Ìràwọ̀ àti ògo mi, tì ọ̀tá ti mú yàbàrà lọ sínú aginjù yóò padà sọdọ mi lónì nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Lónì, ara iná Ọlọ́run yóò parun gbogbo agbára ọ̀tá tí wọ́n yàn láti fa wàrà ayànmọ́ mí mu, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ayọ̀ mi tí ọ̀tá ti bàjẹ́, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, jíndè nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Ìrànlọ́wọ́ àti àtìlẹ́yìn mi tí ọ̀tá tí túká nípa àyídáyidà àlá, gba ìmúpadà bọ̀ sípò nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Onírúrú ìrànlọ́wọ́ Ọlọ́run atòkèwá, tí ó ti jìnà réré sími tẹ́lẹ̀ rí, bẹ̀rẹ̀ siní ṣàwárí mi, ní orúkọ Jésù.
6. Mo sọ di aláìlágbárà, gbogbo ègún àjógúnbá tó n yọ ayé mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
7. Mo gba àṣẹ lórí gbogbo ìmísí òkùnkùn ìdílé nípa ṣẹ̀ olubi, ní orúkọ Jésù.

# <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Isaiah 40:29:** O nfi agbara fun alarẹ; o si fi agbara kun awọn ti ko ni ipa.

**Filippi 4:19:** Ṣugbọn Ọlọrun mi yoo pese ni kikun fun gbogbo aini nyin, gẹgẹ bi ọrọ Rẹ ninu ogo ninu Kristi Jesu.

**Orin Dafidi 107:20:** O ran ọrọ Rẹ, O si mu wọn lara da, O si gba wọn kuro ninu iparun wọn.

**Orin Dafidi 147:3:** O mu awọn onirora aya lara da: O di ọgbẹ wọn.

**Isaiah 57:18-19:** Mo ti ri ọna rẹ, emi o si mu u li ara da: emi o si tọ ọ pẹlu, emi o si mu itunu pada fun u wa, ati fun awọn aṣọfọ rẹ. Emi li o da eṣo ete; Alafia, alafia fun ẹniti o jina rere, ati fun ẹniti o wa nitosi, ni Oluwa wi; emi o si mu u li ara da.

**Romu 8:37:** Ṣugbọn ninu gbogbo nkan wọnyi awa ju ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa.

**Matteu 9:21:** Nitori o wi ninu ara rẹ pe, Bi mo ba sa le fi ọwọ kan aṣọ rẹ, ara mi o da.

**Deutérónómì 7:15:** OLÚWA yóò sì gba àrùn gbogbo kúrò lọ́dọ̀ rẹ. Kì yóò sì fi ọ̀kan nínú àrùn búburú Égíptì, tí ìwọ mọ̀, sí ọ lára, ṣùgbọ́n òn o fí wọ́n lé ara gbogbo àwọn tí ó kórira rẹ.

**Isàíàh 58:8:** Nígbàná ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Jeremíàh 17:14:** Wò mí sàn, Olúwa, èmi ó sì sàn; gbà mí là, èmi ó sì là; nítorí Ìwọ ni ìyìn mi.